


# ÀṢÀ, ÈRÒ ÀTI ÈDÈ NÍNÚ IṢÉ-ỌNÀ ALÁWÒMỌ́ - LÍTÍRÉṢỌ̀ AKÍNWÙMI ÌṢỌ̀LÁ

DÚRÓ ADÉLÉKÈ
Olóòtu

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# ÀṢÀ, ÈRÒ ÀTI ÈDÈ NÍNÚ IṢẸ́-ỌNÀ ALÁWÒMỌ́-LÍTÍRÉṢÒ AKÍNWÙMÍ ÌṢÒLÁ

**OLÓÒTÚ**
**DÚRÓ ADÉLẸ́KÈ**

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

IBADAN
DB MARTOY BOOKS
2016

© *Olóòtú Dúró Adélékè 2016*

Ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ da ohunkóhun kọ láti inú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yàtọ̀ fún ìlò ara tirẹ̀ láìgba àṣẹ lọ́wọ́ òǹkọ̀wé tàbí iléeṣẹ́ aṣèwétà **DB Martoy Books** bí ó ti tọ́ lábẹ́ òfin tó dé ìwé gbígbé jáde

ISBN: 978-978-50689-9-3

A tẹ ìwé yìí jáde láti iléeṣẹ́
**DB Martoy Books**
Plots 5 & 7, Block C
Alhaji Akinlẹyẹ Layout
Papa Zone Ogungbade,
Ibadan, Nigeria.
Tel: 08023133705

*Typesetting by:* Temisayo Ventures, U.I.

*Printed by:* Agoro Publicity Company Ibadan

**DB MARTOY BOOKS, IBADAN**
**2016**

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# ÀKÓÓNÚ


| | | *Ojú ìwé* |
|---|---|---|
| Orí Kìn-ín-ní: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá | 1 |
| Orí Kejì: | Obìnrin Àti Ìmọ̀-Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá Nínú *Kòṣeégbé* | 5 |
| Orí Kẹta: | Ìmẹ̀tọ́ Láwùjọ Yorùbá bí ó ti hàn nínú *Ogún Dé Bodè* | 18 |
| Orí Kẹrin: | Èrò Ọ̀jọ̀gbọ́n Ìṣọ̀lá Akéwì Nípa Ìpapòdà Àwọn Akíkanjú Ọkùnrin Mẹ́ta Ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ | 31 |
| Orí Karùn-ún: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá: Akin Òǹkọ̀wé àti Àwọn Àṣewétà Rẹ̀ | 47 |
| Orí Kẹfà: | Ìsínnijẹ nínú iṣẹ́ ọnà Lítíréṣọ̀ Akínwùmí Orójídé - Ìṣọ̀lá | 66 |
| Orí Keje: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá: Òpìtàn Asọ̀tàn | 85 |
| Orí Kẹjọ: | Àyínìke Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀ Orúkọ Akínwùmí Ìṣọ̀lá Nínú *Fàbú* | 92 |
| Orí Kẹsàn-án: | Ìhà tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ sí Ẹ̀sìn nínú eré-onítàn *Abẹ́ Ààbò* Ní ìlànà Tíọ́rì Aṣàtakò-Ìmúnisìn | 102 |
| Orí Kẹwàá: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá Gẹ́gẹ́ Bí Olùkọ́ni Ní Àṣà | 115 |
| Orí Kọkànlá: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá Adẹ́rìnínpòṣónú: Àgbéyẹ̀wò Àwàdà Ajẹmọ́-ọ̀rọ̀-ìfẹ́ Nínú *Fàbú* | 138 |
| Orí Kejìlá: | Àgbéyẹ̀wò Ìlò Ewì Alohùn Yorùbá Nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá Kọ | 153 |
| Orí Kẹtàlá: | Òǹkọ̀wé, Ìwé Kíkọ àti Èrò Ajẹmọ́-lílò: Ìtúpalẹ̀ lámèyítọ́ Lórí Àwọn Eré-Oníṣe Akínwùmí Ìṣọ̀lá | 162 |
| Orí Kẹrìnlá: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá gẹ́gẹ́ bí Asẹ̀tọ́fábo: Àpẹẹrẹ *Àfàìmọ̀ Àti Àwọn Àròfọ̀ Mìíràn* | 173 |


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

| | | |
|---|---|---|
| Orí Kẹẹ̀ẹ́dógún: | Ìlò-Èdè Nínú Ìwé Ìtàn Àròsọ *'Ó Le Kú'* | 187 |
| Orí Kẹrìndínlógún: | Ìmójúwáyé Olùkọ́ àti Iṣẹ́ Olùkọ́ Nínú *Ó Le Kú* àti *Ogún Ọmọdé* | 205 |
| Orí Kejìdínlógún: | Ète Iṣàtakò Ìmúnisìn Nínú Eré-Onítàn Yorùbá: Akínwùmí Ìṣọ̀lá Àti Adébáyọ̀ Fálétí Gẹ́gẹ́ Bí Àpẹẹrẹ | 216 |
| Orí Kejìdínlógún: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá Akéwì | 229 |
| Orí Kọkàndínlógún: | Àwọn Orin Fíìmù *Ṣaworoide* Àti *Agogo Èèwọ̀* Gẹ́gẹ́ Bí Awòjìji Ìṣẹ̀lẹ̀ Ilẹ̀ Wa | 242 |
| Orí Ogún: | Ìfàmìpàrokò Nínú Fíìmù *Ṣaworoide* àti *Agogo Èèwọ̀* | 260 |
| Orí Kọkànlélógún: | Ìkọlura àti Ìtàpórógan Nínú Àwọn Àṣàyàn Fíìmù Akínwùmí Ìṣọ̀lá | 270 |
| Orí Kejìlélógún: | Àgbéyẹ̀wò Àwọn Akọnibìnrin Olú-Ẹ̀dá-Ìtàn Ajẹmọ́tàn-Gidi Nínú Eré-Onítàn Akínwùmí Ìṣọ̀lá | 281 |
| Orí Kẹtàlélógún: | Ìlò Lítíréṣọ̀ Alohùn Nínú *Ogún Ọmọdé* | 295 |
| Orí Kẹrìnlélógún: | Akínwùmí Ìṣọ̀lá: Láríjà Ìṣàmúlò Ìdánilọ́kànró fún Àkọlé Orúkọ Ìwé Ìtàn Àròsọ *Ó Le Kú* | 307 |
| Orí Kẹẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n: | Bátànì Ìgbékalẹ̀ Àti Ìpèdè Àwàdà Nínú Ìwé Akínwùmí Ìṣọ̀lá – *Fàbú* | 317 |
| Orí Kẹrìndínlọ́gbọ̀n: | Ojú tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi wo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá nínú "*Àfàìmọ̀ Àti Àwọn Àròfọ̀ Mìíràn*" | 338 |
| Orí Kẹtàdínlọ́gbọ̀n: | Ìṣàtúnṣe Ìwà Ẹfúnṣetán Aníwúrà Nínú Fíìmù Akínwùmí Ìṣọ̀lá | 351 |

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Orí Kejìdínlọ́gbọ̀n: Àdàpè: Ọ̀kan Lára Ọ̀pọ́ tó gbé Iṣẹ́ Ọnà Akínwùmí Ìṣọ̀lá ró 366

Orí Kọkàndínlọ́gbọ̀n: Ìṣọ̀lá Afigègé Dárà! Ìyiri Ìfọ̀rọ̀dárà Inú "Àtàtamọ́ Àtàtamọ̀ I" Nínú *Àfàìmọ̀ Àti Àwọn Àròfọ̀ Mìíràn* 379

Orí Ọgbọ̀n: Ìfèdèwẹ̀dá Nínú *Kọ̀ṣeégbé* 389

Orí Kọkànlélọ́gbọ̀n: Ìlò Orin nínú Àwọn Fíìmù Àgbéléwò Akínwùmí Ìṣọ̀lá 402

Orí Kejìlélọ́gbọ̀n: Akínwùmí Ìṣọ̀lá: Alóre Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá Nínú Ìwé Ìtàn *Ogún Ọmọdé* 411

Orí Kẹtàlélọ́gbọ̀n: Ìlò Orin Nínú Àwọn Ìwé Àtinúdá Akínwùmí Ìṣọ̀lá 423

Orí Kẹrìnlélọ́gbọ̀n: Àfojúsùn Akínwùmí Ìṣọ̀lá Gẹ́gẹ́ Bí Òǹkọ̀wé Ìtàn Àròsọ 432

Orí Karùndínlógóji: Ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ nínú àṣàyàn orin inú fíìmù *Campus Queen* 448

Orí Kẹrìndínlógóji: Àrà tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi kóòdù àti Ọ̀rọ̀-ayálo dá nínú *Ó le kú* 459

Orí Kẹtàdínlógóji: Ìṣàfihàn ipa òbí àti ìwà ọ̀dọ́ nínú fíìmù *Ó Le Kú* 469

Orí Kejìdínlógóji: Lílo Orin láti gbé kókó-ọ̀rọ̀ jáde nínú Ìwé Eré-Onítàn *Ẹfúnróyè Tinúbú* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ 486

Orí Kọkàndínlógóji: Ìhà tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ sí Ẹgbẹ́ Ajàjàgbara tó ń jà fún Ẹ̀tọ́ àti Ètò Ìlú nínú Ìwé *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* 498

Orí Ogójì: Ìṣọ̀lá pé Àádọ́rin Ọdún 507

**Orúkọ Àwọn Òǹkọ̀wé Akópa** 509

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# Orí Kẹrìndínlógún

## Ìmójúwayé Olùkọ́ àti Iṣẹ́ Olùkọ́ Nínú *Ó Le Kú* àti *Ogún Ọmọdé*

***Adéyẹmí Adéyínká***

**Ìfáárà**

Onírúurú ni àwa ẹ̀da t'Élédùmarè ṣe lọ́jọ̀ sínú ayé bẹ́ẹ̀ ni kálùkù ní òmìnira àti gbé òkè èrùpẹ̀ ṣe ohun ti ó wù ú. Bí a ṣe rí àwọn tí wọ́n wáyé wá ṣe rere náà ni àwọn aṣebi wà nínú rẹ̀ ṣùgbọ́n gbogbo ohun tí ẹ̀dá bá gbélé ayé ṣe ni yóò jíyìn rẹ̀ nígbà tí àkókò ìṣírò bá dé. Ilé ayé kò lọ títí bẹ́ẹ̀ ni ìgbà ń yí padà nínú ayé ṣùgbọ́n iṣẹ́ ọwọ́ ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ni yóò dá a lẹ́jọ́ nígbà tí ó bá yá. Ẹnìkọ̀ọ̀kan ni ó ń kọ ìtàn ara rẹ̀ bí ilẹ̀ ti ń mọ́ tí ó sì ń ṣú. Ohun tí kálukú ṣe yóò fojúhàn bó pẹ́, bó yá nítorí pé "àṣeélẹ̀ ni àbọ̀wábá" ohun yòówù tí a bá ṣe lónìí, ìtàn ni yóò dà bó bá di ọ̀la nítorí náà ni a ṣe gbọ́dọ̀ se é e re kó lè dára.

Ohun yòówù tí ẹ̀dá lè sọ nípa Ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùmí Ìṣọ̀lá lónìí dá lórí gbogbo ohun tí ó gbé ilé ayé ṣe, yálà nípa àkọọ́lẹ̀ nípa rẹ̀, ohun tí àwọn ènìyàn ti rí nígbà tí wọ́n jọ ń rìn tàbí ṣiṣẹ́ àti nípa ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú rẹ̀. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ni ìrírí Akínwùmí Ìṣọ̀lá èyí tí ó fi ara hàn nínú àwọn ìwé tí ó ti kọ ṣùgbọ́n ohun tí ó jẹ́ àfojúsùn ìwé yìí ni ojú tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi wo iṣẹ́ olùkọ́ nínú àwọn ìwé rẹ̀ méjì, *Ó Le Kú* àti *Ogún Ọmọdé.*

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "ẹni tí ó fẹ́ dá aṣọ fúnni, ti ọrùn rẹ̀ ni à ń wò" Akínwùmi Ìṣọ̀lá fúnra rẹ̀ kì í ṣe ọ̀gbẹ̀rì nínú iṣẹ́ olùkọ́, ọjọ́ àbọ́kí rẹ̀ pẹ́ ní eégún. Iṣẹ́ tí Ọjọ̀gbọ́n yìí yàn láàyò láti òwúrọ̀ ọjọ́ wá ni, ẹnu rẹ̀ ni ó di irún di igba sí, iṣẹ́ tí ó ṣe tí ó fi gbé ìyàwó tí Olódùmarè sì fi ọmọ rere jìnkí wọn ni. Ó jẹ iṣẹ́ tí ó ṣe dé góńgó tí ó si fi tayọ̀tayọ̀ fẹ̀yìntì lẹ́nu rẹ̀ ní ìpele ẹ̀kọ́ tí ó ga jù lọ. A gbàgbọ́ pé bí a bá wo iṣẹ́ olùkọ́ nínú *Ó Le Kú* àti *Ogún Ọmọdé,* a ó lè ṣe ìgbéléwọ̀n tí ó yẹ lórí iṣẹ́ olùkọ́ lóde òní.

**Taa ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá?**

Onírúurú ìwádìí àti ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí Akínwùmí Ìṣọ̀lá. Ọpádọ̀tun (2003) àti Akínyẹmí pẹ̀lú Fálọlá (2008) ti ṣe àkọsílẹ̀ tí ó kún lórí igbé ayé Akínwùmí Ìṣọ̀lá. Wọ́n ti jẹ́ ki ó di mímọ̀ fún aráyé pé ọjọ́ kẹrìnlélógún oṣù kejìlá ọdun 1939 ni a bí i àtipé èyí ni o fa sábàbí tí àwọn

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

òbí rẹ̀ fi sọ ọ́ ní Abọ́dúnrìn nítorí pé elésìn ọmọlẹ́yìn Jésù ni àwọn òbí rẹ̀, bàbá rẹ̀ sì nì ó mú ìjọ Elétò wọ abúlé Lábọ̀dé tí í ṣe abúlé wọn.

Akínwùmí Ìṣọ̀lá jẹ àǹfààní pé bàbà rẹ̀ ni ó mú ìjọ Ọlọ́run wọ abúlé wọn nítorí pé ó tètè bẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí Ìjọ Elétò da silẹ̀ ní abúlé Lábọ̀dé ó sì parí rẹ̀ ni Methodist Primary School, Agodi, Ìbàdàn ni 1951. Àkọsílẹ̀ fi yé wa pé Akínwùmí ní àǹfààní láti wọ ilé-ẹ̀kọ́ girama Ìbàdàn Grammar School lẹ́yìn ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ṣùgbọ́n owó já a ní tànmọ́ọ̀n ẹ̀yí tí ó mú un bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ olùkọ́. Láàrin oṣù kìn-ín-ní ọdún 1953 sí oṣù kejìlá ọdún 1954, Akínwùmí Ìṣọ̀lá lọ sí ilé ẹkọṣẹ olùkọ́ onípò kẹta ní Ìfàkì-Èkìtì. Ó tẹ̀síwájú láti gba ìwé-ẹ̀rí olùkọ́ onípo kejì nípa lílọ sí Wesley College Ìbàdàn. Ó gba íwé-ẹ̀rí àkọ́kọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga ti Yunifásítì Ìbàdàn nínú èdè Faransé. Ó gba ìwé ẹ̀rí dípúlómà nínú ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè ó sì gba oyè kejì nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá àti oyè ọ̀mọ̀wé nínú lítíréṣọ̀ ti o jẹ mọ́ ìtàn àròsọ.

Bí a bá wo àwọn ìwé ẹ̀rí Akínwùmí Ìṣọ̀lá, ó hàn kedere pé orí ni ó mú wọ iṣẹ́ olùkọ́ kì i ṣe àṣàwọ̀ bẹ́ẹ̀ ni kò fi ṣe àbọ̀ṣẹ́ rárá. Láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ tí ènìyàn ti ń ṣe iṣẹ́ yìí ní ó ti mú un ó sì gbé óúnjẹ fún ẹgbẹ́, ó gba awo bọ̀ nínú rẹ̀. Ìwé ẹ̀rí olùkọ́ onípo kẹta àti onípo kejì pẹ̀lú ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìrírí rẹ̀ lẹ́nu iṣẹ́ yìí ni ó hànde nínú *Ó Le Kú àti Ogún Ọmọdé* tí iṣẹ́ yìí ń ṣe agbéyẹ̀wò rẹ̀.

**Ìrírí Akínwùmí Ìṣọ̀lá bí Olùkọ́**

Láìfì ọ̀pá pọ̀ọ̀lọ̀pọọlọ pa ejò, Akínwùmí ti mọ ẹ̀wà ní oúnjẹ àjẹsùn láti kékere nítorí àkọsílẹ̀ fi yéni pé nígbà tí ó jáde ìlé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí kò sì sí owó láti rán an lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ girama ni àwọn àgba ìjọ Elétò ti fi orí ìkookò ṣe ọ̀ọ́dúnrún tí wọ́n ni kí o bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ olùkọ́ ni ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ìjọ Elétò tí ó wà ní Olódó ní oṣù kìn-ín-ní ọdún 1952. Lẹ̀yìn ọdún kan tí ó fi ṣe iṣẹ́ olùkọ́, ó lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ ní Ìfàkì-Èkìtì ó sì padà sí ẹnu iṣẹ́ olùkọ́ ní oṣù kìn-ín-ní ọdún 1955.

Láàrín 1955 sí 1956, Akínwùmí ṣè iṣẹ́ olùkọ́ ní Ìgàn Òkòtó àti Ìgbógílà ní agbègbè Yewa ní Ìpínlẹ̀ Ògùn bẹ́ẹ̀ náà ni ó ṣe iṣẹ́ olùkọ́ ní ilé ẹ̀kọ́ Mọdá tí ó jẹ́ ti Ìjọ Elétò ní ìlú Ògbómọ̀ṣọ́. Iṣẹ́ olùkọ́ yìí náà tún gbé Akínwùmí Ìṣọ̀lá dé ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ Wesley ní Ìbàdàn ni 1957 bẹ́ẹ̀ ni ó padà sí ilé-ẹ̀kọ́ yìí lẹ́yìn ìgbà tí ó gba oyè àkọ́kọ́ ni Yunifásítì ní oṣù kẹsàn-án ọdún 1967.

Láti oṣù kẹrin ọdún 1968 ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá ti di olùkọ́ kékeré ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga ti ìlú Èkó tí ó si ti ń fi ìmọ̀ kún ìmọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè àti àṣà

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Yorùbá. Akínwùmí Ìṣọ̀lá kùró ní Yunifásítì Èkó lọ sí ti Ilé-Ifẹ̀ láti tẹ̀ síwájú nínú iṣẹ́ ìkọ́ni ó sì gòkè àgbà láti di ọ̀jọ̀gbọ́n nínú iṣẹ́ yìí títí di ọdún 1991 tí ó fi ẹ̀yìn tì lẹ́nu iṣẹ́ ìjọba.

Bí a bá wo ṣàkun ìrírí Akínwùnmí Ìṣọ̀lá gẹ́gẹ́ bí olùkọ́, a ó rí i pé láti ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ títí dé ilé-ẹ̀kọ́ yunìfásìtì nì ó ti ṣe iṣẹ́ yìí. Ìṣọ̀lá kì í ṣe ọ̀gbẹ̀rì nínú iṣẹ́ olùkọ́ nítorí pé ó tì ní ìmọ̀, ìwé ẹ̀rí àti ìrírí tí ó yẹ èyí nì ó mú kí ó dáńtọ́ nínú iṣẹ́ olùkọ́ni. Ọkan-ò-jọ̀kan ìrírí tí ó ní ní abúlé Lábọ̀dé pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ àti àwọn ibi tí ó tì pilẹ̀ iṣẹ́ olùkọ́ kò sàìhàn nínú iṣẹ́ rẹ̀ tí a yẹ̀wò nínú àpilẹ̀kọ yìí.

## Taa ní Olùkọ́?

A lérò pé kò ní bójúmu láti máa ṣe atótónu lọ́rì kókó iṣẹ́ yìí láìwo ẹni tí olùkọ́ ń ṣe. Onírúurú àlàye ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lọ́rí ẹni tí a lè pè ní olùkọ́ nítorí pé ó jẹ́ àwòkọ́ṣe fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ìwà àti ìṣe rẹ̀ sì ń kó ipa lọ́rí títún àyànmọ́ àwọn aṣíwájú ọjọ́ ọ̀la orílẹ̀-èdè ṣe, bí ó bá ṣe dáadáa, tàbí kí ó bà á jẹ́, bí kò bá ṣe dáadáa.

A kò lè sọ pàtó pé ohun báyìí ní Lágbájá sọ nípa olùkọ́ tàbí báyìí ni Tàmẹ̀dù wí nípa rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí ṣùgbọ́n a ó fi ọ̀ṣùwọ̀n tí Afọláyan (2008) gbé kalẹ̀ ṣe àlàyé ẹni tí olùkọ́ jẹ́. Jedo (1981) náà ti ṣe àlàyé ṣíwájú lọ́rí àwọn àbùdá tí a lè rí nínú ẹni tí a bá pè ní olùkọ́ tí ó peregedé.

Afọláyan (2008) gbé àwòmọ́ méje kalẹ̀ tí olùkọ́ tí ó gbé oúnjẹ fún ẹgbẹ́ tí ó sì gba awo bọ̀ gbọ́dọ̀ ní. Àwòmọ́ àkọ́kọ́ ni pé irúfẹ́ olùkọ́ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìṣòtítọ́. Èyí túmọ̀ sí pé olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ olótìítọ́ sí ara rẹ̀; ó gbọ́dọ̀ jẹ́ olótìítọ́ sí àwọn olùkọ́ ẹgbẹ́ rẹ̀ àti sí àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Olùkọ́ gbọ́dọ̀ rìn nínú òtítọ́, kí "bẹ́ẹ̀ ni" rẹ̀ jẹ́ "bẹ́ẹ̀ ni", kí "bẹ́ẹ̀ kọ́" rẹ̀ sì jẹ́ "bẹ́ẹ̀ kọ́". Olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí wọ́n ń bá ọ̀rọ̀ rẹ̀ bẹ́ẹ̀, kì í ṣe dandan nì kí ó jẹ́ pé ohun rere ni olùkọ́ ṣe kí ó tó sọ òtítọ́ ṣùgbọ́n bí olùkọ́ bá ṣe àṣìṣe, ó gbọ́dọ̀ lè sọ òtítọ́ pé òun ni òun ṣe é.

Síwájú sí ì, àwòmọ́ kẹ̀jì tí Afọláyan gbé kalẹ̀ fún olùkọ́ nì ìrànlọ́wọ́. Èyí ni pé olùkọ́ gbọ́dọ̀ ṣe tán láti ran àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ lọ́wọ́ nítorí ohun tí ó yẹ kí ó jẹ́ é lógún jù ni bí púpọ̀ nínú áwọn akẹ́kọ̀ọ́ òun yóò ṣe peregedé nínú ẹ̀kọ́ wọn. Nípa sísúnmọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ni olùkọ́ yóò ṣe mọ àwọn àléébù tí wọ́n ní nínú ìkẹ́kọ̀ọ́, ìmọ̀ tí ó sì ní ni yóò lò láti mọ ìrú ọgbọ́n ìkọ́ni tí ó lè lò láti ràn wọ́n lọ́wọ́.

Àwòmọ́ kẹta nì ìṣepàtàkì. Ó ṣe é ṣe kí akẹ́kọ̀ọ́ má mọ pàtàkì ẹ̀kọ́ tí ó ń kọ́ ṣùgbọ́n ojúṣe olùkọ́ nì láti fi pàtàkì ẹ̀kọ́ tí akẹ́kọ̀ọ́ ń kọ́ hàn án. Èyí

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

wúlo púpọ̀ láti tètè ṣí ojú akẹ́kọ̀ọ́ sí iṣẹ́ àṣelà rẹ̀ kí olùkọ́ sì tọ́ ọ sọ́nà lórí àwọn iṣẹ́ tí ó lè mú un ṣe àmúṣẹ èròǹgbà rẹ̀ ọjọ́ ọ̀la.

Bákan náà, kòṣeémánìí jẹ́ àwomọ́ tí a gbọ́dọ̀ rí lára olùkọ́ tí ó peregedé. Olùkọ́ gbọ́dọ̀ rí ìṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí kànńpá èyí tí òun gbọ́dọ̀ mú ní ìbáádà. Ó gbọ́dọ̀ fi ìfẹ́ tí ó ní sí iṣẹ́ yìí hàn nípa lílọ sí kíláàsì lásìkò bẹ́ẹ̀ ni kò gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ohun mìíràn pa igi dí ọ̀nà iṣẹ́ tí òun yàn láàyò. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ìdákúrekú owó ọ̀yà ti mú kí olùkọ́ mìíràn fa iṣẹ́ yìí lọ́wọ́ kí wọn sì gbé okòwò wọn lórí èyí sì ń mú wọn káràmásìkí okòwò wọn ju iṣẹ́ olùkọ́ lọ.

Kò pin sí ibí yìí, olùkọ́ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìfiféhàn. Olùkọ́ tí yóò yanranntí gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìfẹ́ nítorí pé aṣeyọrí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ ni àṣeyọrí rẹ̀. Ó gbọ́dọ̀ fi ìfẹ́ hàn sí àwọn akẹ́kọ̀ọ́, lọ́gbọọgba. Èyí ni pé kì í ṣe akẹ́kọ̀ọ́ tí ó jáfáfá tí ó sì mọ̀wé nìkan ni ó gbọ́dọ̀ fẹ́ràn ṣùgbọ́n ó gbọ̀dọ́ ṣetán láti ran àwọn tí ó kù díẹ̀ káàtó náà lọ́wọ́ nípa lílo onírúurú ọgbọ́n ìkọ́ni àti ohun ètò ìkọ́ni ki àwọn náà le yege nínú ẹ̀kọ́ wọn.

Síwájú sí i, olùkọ́ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìlálòpẹ́. Olùkọ gbọ́dọ̀ mọ̀ pé ìdìde, ìpìlẹ̀ àyíká àti ìrírí akẹ́kọ̀ọ́ kò dọ́gba èyí ni yóò sì kó ipa lórí ìmọ̀ tí wọ́n ni nítorí náà, ó gbọ́dọ̀ máa farada gbogbo ohun tí ó bá bá pàdé pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ẹ̀mí ìlálòpẹ́ yìí ni yóò mú kí akẹ́kọ̀ọ́ súnmọ́ olùkọ́ kí ó sì ṣípayá ọkàn rẹ̀ fún un èyí tí yóò ràn án (olùkọ́) lọ́wọ́ láti wa ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro yòówù tí ó ń kojú akẹ́kọ̀ọ́.

Àwòmọ́ tí o gbèyìn tí Afọláyan mẹ́nu bá nípa olùkọ́ ni ìbámu-kókó-ìmọ̀. Èyí dá lórí kókó tí olùkọ́ fẹ́ kí akèkọ̀ọ́ mọ̀, ìdí tí akẹ́kọ̀ọ́ fi ń lo kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù tí ó ń ló ní ìpele ẹ̀kọ́ àti èròǹgbà tí ó rọ̀ mọ́ ẹ̀kọ́ náà. Ìbámu-kókó-ìmọ̀ yìí nì yóò ran olùkọ́ lọ́wọ́ láti mọ irú ìmúrasílẹ̀ tí ó yẹ fún ẹ̀kọ́ àti ọ̀nà tí òun yóò gbà mú èròǹgbà yìí ṣẹ.

Láìṣe àní-àní, àwọn àwòmọ́ wọ̀nyí ṣe kókó fún olùkọ́ yòówù, ní ìpele ẹ̀kọ́ yòówú tí ó ń kọ́ nítorí àwọn ni yóò mú kí mùṣèmúṣè rẹ̀ dá múṣémúṣé tí yóò sì mú kí ìran àti èròǹgbà rẹ̀ yọrí sí rere. Àwọn àwòmọ́ yìí ni Afọláyan gbé kalẹ̀ tí ó sì fi ṣe òdiwọ̀n Akínwùmí Ìṣọ̀lá kí ó tó fi ẹnu ọ̀rọ̀ náà jọ̀nà sí pé olùkọ àgbà tí ó fi ogún mánigbàgbé sílẹ̀ fún ẹ̀dá ni. Àlàyé Afọláyan yìí ní yóò mú wa wo olùkọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá ní ayé ọjọ́un àti ní òde òní gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àwọn ìwé méjì tí iṣẹ́ yìí ń ṣe àgbéyẹ̀wò wọn. A lérò pé èyí yóò ràn wá lọ́wọ́ láti yànnàná ojú tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá fi wo iṣẹ́ yìí pàápàá jù lọ nígbà tí ó jẹ́ iṣẹ́ tí ó yàn láàyò.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**Olùkọ́ láyé Ọjọ́un**

Bí ilẹ̀ ti ń ṣú, tí ilẹ̀ ń mọ́ ni onírúurú ohun ọ̀tun ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ àṣùwàdà. Gbogbo ẹ̀ka-ètò ìṣèlú, ọrọ ajé, ọ̀gbìn, ìlera, ẹ̀kọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni ìdàgbàsókè ń dé bá. Oríṣìíríṣìí ohun ọ̀tun ni àwọn onímọ ń ṣe àwárí rẹ̀ tí wọ́n sì ń ṣe àfihàn rẹ̀ fún aráyé ṣùgbọ́n èyí kò ní kí á gbàgbé ìṣẹ̀ṣe nítorí èyí ni kò ni jẹ́ kí á sọnù kí à tó sọnú.

Ọ̀kan lára iṣẹ́ tí ó kọ́kọ́ gbilẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá nígbà tí ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Jésù dé ni iṣẹ́ olùkọ́ nítorí pé àwọn òyìnbó mú méjèèjì dé sí àwùjọ Yorùbá nígbà kan náà ni. Ète tí wọ́n fi dá ilé-ẹ̀kọ́ sílẹ̀ ni láti jẹ́ kí àwọn ọmọ adúláwọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ, mọ̀-ọ́n-kà ṣùgbọ́n Bíbélì gan-an ni wọ́n fẹ́ kí wọ́n mọ́ ọ́n kà jù. Ẹnikẹ́ni ti Olódùmarè ba fún ní àǹfààní láti jáde ìwé mẹ́fà ní ayé àtijọ́ ti kúrò ní púrúǹtù nítorí èyí yóò fún un ní àǹfààní láti ṣe iṣẹ́ ìjọba tàbí iṣẹ́ olùkọ́ níbì tí yóò ti máa gba owó ọ̀yá ní oṣooṣù.

Nínú *Ogún Ọmọdé* (1990), Ìṣọ̀lá jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé ìwé ẹ̀rí oníwèé mẹ́fà lásán ti tó láti sọ ènìyàn di olùkọ́ ní ọjọ́ ọjọ́un. Ní kété tí ènìyàn bá ti jáde ìwé mẹ́fà, wọ́n lè gbé e lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ láti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ olùkọ́.Ìṣọ̀lá fi ìdí èyí múlẹ̀ pé:

> Tíṣà kẹrin ló kéré jùlọ nínú wọn, ó
> ṣẹ̀ṣẹ̀ jáde ìwé mẹ́fà ni Elékùrọ́ ní
> Ìbàdàn ni. A máa ń pè é ní tíṣà kékeré (o.i.48)

Bí ó tì wù kí ìwé ẹ̀rí ìgbanisíṣẹ́ kéré tó lọ́jọ́ ọjọ́un, igbákejì Olódùmarè nì àwọn ará ìlú ka olùkọ́ sí. Wọ́n gbàgbọ́ pé wọ́n ti ní ìmọ̀ àti ìrírí tí ó tayọ àtipé wọ́n súnmọ́ àwọn òyìnbó nínú àṣà àti ìṣe wọn nítorí náà, ipò ọlá, ọlà, iyì àti ẹ̀yẹ ni àwọn ará ìlú to olùkọ́ sí.

Àwọn òbí bọ̀wọ̀ fún àwọn olùkọ́ tóbẹ́ẹ̀ tí wọ́n rí ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá sọ gẹ́gẹ́ bí èyí ti ó ti ẹnu òrìṣà jáde. Nígbàkúgbà tí ọmọ bá hu ìwà àìtọ́, àwọn òbí a máa fi olùkọ dẹ́rù ba akẹ́kọ̀ọ́ pé àwọn yóò lọ fi ẹjọ́ rẹ̀ sùn. Ohun tí ó fa sábàbí èyí ni pé olùkọ́ ayé ọjọ́un ní òmìnira láti lo ẹgba bẹ́ẹ̀ ni kò sí òbí tí ó lórí láyà láti lọ bá olùkọ́ pé ó ṣe na ọmọ òun. Ìṣọ̀lá kín èyí lẹ́yìn nínú *Ogún Ọmọdé* nígbà tí ó ṣe àlàyé pé:

> Ẹrù ọ̀rẹ́ ni à máa ń rù lọ sí ilẹ̀-ìwé, ara wa ni
> gbogbo rẹ̀ máa ń gbó sí... Àrísá iná ni tíṣà,
> àkòtagìrì ejò. Bí tíṣà bá ń bọ̀ lọ́ọ̀ọ́kán, gbogbo
> àwọn ọmọ ilé-ìwé á túká ni (o.i.47).

Ní ayé ọjọ́un, ara àyẹ́sí tí àwọn òbí ń fún olùkọ ni pípèsè oúnjẹ fún wọn. Ó jẹ́ àṣà fún àwọn tí ó wà ní abúlé láti dá irè oko bí iṣu, àgbàdo, èlùbọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́è lọ jọ kí wọ́n sì gbé e lọ sí ilé tí ìlú gbà fún àwọn olùkọ́.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ní abúlé tí wọn kò bá ti dá irè oko jọ, wọn yóò máa gbé oúnjẹ́ lọ fún wọn ni ojoojúmọ́. Wọ́n ń ṣe èyí láti fà wọ́n mọ́ra nítorí òyé tí wọ́n ní pé wọ́n ń fi kún ìmọ̀ àwọn ọmọ wọn.

Kì í wá ṣe pé "múwá, múwá" bi apa ẹyẹlé ni ọ̀rọ̀ yìí jẹ́ lọ́dọ̀ àwọn olùkọ́. Nígbàkúgbà tí àwọn olùkọ́ náà bá rìn ìrìnàjò lọ sí ìgboro ni wọ́n máa ń ra búrẹ́dì wá fún àwọn ará oko èyí tí ó túmọ̀ sí pé "Gbà fún Gbàdà nílé ni gbà fún Gbàdà lóko". Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn òbí máa ń lọ ṣe "ẹ ǹ lẹ́ ń bẹ̀un" sí àwọn olùkọ́ ní ilé wọn láti túbọ̀ yẹ́ wọn sí.

Kìí ṣe pé àwọn òbí ń gbé oúnjẹ lọ fún àwọn olùkọ́ nìkan, àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ ń jẹ́ oríṣìíríṣìí iṣẹ́ fún wọn yálà ní àsìkò ẹ̀kọ́ tàbí nígbà tí wọ́n bá jáde ilé-ẹ̀kọ́. Àwọn olúkọ̀ ń bẹ akẹ́kọ̀ọ́ ní igi láti dá iná bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń ní kí wọ́n mú oríṣìíríṣìí ohun tí ẹnu ń jẹ wá láti kọ́ ẹ̀kọ́. Ìṣọ̀lá fi ìdí èyí múlẹ̀ pé:

> Bó bá sì tún di ìgbà òjò, wọn a ní a fẹ́ẹ̀ kọ́ ẹ̀kọ́ nípa ìgbín àti ìlákọ̀, nítorí náà kí oníkálukú mú mẹ́fà-mẹ́fà wá. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, wọn a ní kí á mú ata agolo kọ̀ọ̀kan wá, kí aya tíṣà róun sebẹ, kò róun mú relé (o.i.67)

Ohun mìíràn tí a ṣe àkíyèsí nípa olùkọ́ ní ayé ọjọ́un ni nípa ìmúra wọn. Ìṣọ̀lá jẹ́ kí ó hàn pé àwọn olùkọ́ máa ń múra dáadáa wọ́n a wọ ṣòkòtò gígùn pẹ̀lú ṣẹ́ẹ̀ti pẹ̀lú bàtà aláwọ̀tán. Wọ́n tún máa ń de táì. Ní ìgbà mìíràn, olùkọ́ tàbí ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ lè wọ ṣòkòtò pénpé pẹ̀lú ìbọ̀sẹ̀ tí ó dé orúnkún wọn. Wọ́n máa ń fi kálámù àti lẹ́ẹ̀dì há ẹ̀sẹ̀. Ìmúrà yìí jẹ́ ohun ìwúrí fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ ni ó hàn pé olúkọ̀ gbọdọ̀ jẹ́ àpẹẹrẹ rere fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

Ṣíwájú sí ì, a rí i nínú *Ogún Ọmọdé* pé ojúṣe ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ ní láti pín iṣẹ́ fún àwọn olùkọ́. A rí i pé ọ̀tọ̀ ni ẹni tí ó wà nídìí iṣẹ́ àgbẹ̀, ọ̀tọ̀ ni ẹni ti ó wà nídìí orin kíkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ojúṣe yìí ni ó ń ran ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ lọ́wọ́ láti ṣe àmójútó iṣẹ́ tí ó kù kí ohun gbogbo sì lọ déédé ní ilé -ẹ̀kọ́. Àǹfààní mìíràn tí èyí ń mú wá ni pé ó ń jẹ́ ẹ̀kọ́ fún olùkọ́ kọ̀ọ̀kan láti mọ bí a ṣè ń ṣe àkóso nítorí ìgbà tí àgbà yóò kàn wọ́n.

Àléébù gbòógì tí iṣẹ́ olùkọ́ ní ayé ọjọ́un ní wà lọ́wọ́ ìwé ẹ̀rí oníwèé mẹ́fà tí wọ́n fi ń bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́. Sábàbí èyí ni pé irúfẹ́ olùkọ́ bẹ́ẹ̀ kò ní ìmọ̀ tàbí ìrírí nípa ọgbọ́n ìkọ́ni nígbà tí èyí bá sì wáyé, Ìṣọ̀lá nínú *Ogún Ọmọdé* (1990:56) fi yé wa pé olùkọ́ tí kò bá ní ẹ̀bùn ìkọ́ni máa ń tètè bínú, bẹ́ẹ̀ ni nígbà tí irú olùkọ́ bẹ́ẹ̀ kò bá mọ ìdáhùn sí ìbéère akẹ́kọ̀ọ́, wọn kìí fẹ́ jẹ́ kí



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í fẹ́ sọ òtítọ́ nítorí náà, wọ́n á fi ògbójú pa akẹ́kọ̀ọ́ ní ẹnu mọ́.

Ohun mìíràn tí ó fi ara hàn nípa iṣẹ́ olùkọ́ ní ayé ọjọ́un ni pé àwọn olùbẹ̀wò máa ń bẹ ilé-ẹ̀kọ́ wò lóòrèkóòrè èyí sì ń mú kí àwọn olùkọ́ gbáradì kí wọ́n sì jáfáfá lẹ́nu iṣẹ́. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn olùbẹ̀wò kìí sọ tẹ́lẹ̀ kí wọ́n tó wá sí ilé-ẹ̀kọ́ ṣùgbọ́n nígbà tí wọ́n bá ránńṣẹ́, ìgbáradì tí ó lékenkà máa wáyé èyí sì ń ran olùkọ́ lọ́wọ́ láti mú àwọn kùdìẹ̀, kudiẹ tí ó wà kúrò.

**Olùkọ́ Lóde Òní**

Ohun gbogbo ni àyípadà àti ìdàgbàsókè ń dé bá ní àwùjọ lónìí nítorí ọ̀làjú tí ó dé èyí kò sì yọ iṣẹ́ olùkọ́ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ìṣọ̀lá ṣe ṣe àfihàn rẹ̀ nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ ti a gbé yẹ̀wò. A ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá tí a rí nínú àwọn olùkọ́ òde òní a ó sì gbé wọn sí ẹ̀gbẹ́ àwọn olùkọ́ ayé àtijọ́ láti ṣe àlàyé lórí bí iṣẹ́ olùkọ́ ṣe lè túbọ̀ di ìtẹ́wọ́gbà ní àwùjọ wa.

Ohun àkọ́kọ́ tí a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí kòṣeemánìí fún ẹni tí ó bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ olùkọ́ ní òde òní ni pé onítọ̀ún gbọ́dọ̀ ní ìwé ẹ̀rí onípo kejì, ó kéré jù. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìwé ẹ̀rí olùkọ́ni àgbà onípò kìn-ín-ní ni *Àgbékalẹ̀ Ètò Ẹ̀kọ́ Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà* (2004) là sílẹ̀ lónìí, ìwé ẹ̀rí onípò kejì ni ó kéré jù lọ tí ìjọba fi ń gba èniyàn sí iṣẹ́ olùkọ́ ní àkókò tí Ìṣọ̀lá kọ *Ó Le Kú* (1974). A fi ìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí Àjàní pàdé Ṣadé nínú *Ó Le Kú* tí ó sọ fún Àjàní pé;

> Ṣebí mo ṣẹ̀ṣẹ̀ jáde ní Ilé-ẹ̀kọ́ Olùkọ́ tàwọn obìnrin ni, ìbẹ̀rẹ̀ ọdún yìí náà ni mo bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ kẹ (o.i. 54)

Yàtọ̀ sí àwọn ìlé-ẹ̀kọ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ aládàání kọ̀ọ̀kan tí ó ń gba àwọn oníwèé mẹ́wàá sí iṣẹ́ lónìí, púpọ̀ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìjọba ni ó jẹ́ pé àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ olùkọ́ ni ó ń kọ́ àwọn ọmọ. Àwọn tí ó tilẹ̀ ń kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé ẹ̀kọ́ girama olọ́dún-mẹ́ta ẹ̀ekejì máa ń jẹ́ àwọn tí ó ti jáde ní yunifásítì gẹ́gẹ́ bí Àjàní ṣe jáde (o.i. 80).

Síwájú sí i, iṣẹ́ olùkọ́ ní òde òní fẹ́rẹ̀ dà bí iṣẹ́ obìnrin nítorí pé àwọn obìnrin ti pọ̀ lẹ́nu rẹ̀ ju ti ayé ọjọ́un lọ. Gẹ́gẹ bí àpẹẹrẹ, nínú *Ó Le Kú,* àwọn ọ̀rẹ́bìnrin Àjàní bí Àṣàkẹ́ àti Ṣade jẹ́ olùkọ́. Ó dàbí ẹni pé iṣẹ́ náà ti wá di ti àwọn obìnrin ní òde òní yàtọ̀ sí ayé àtijọ́ tí ó jẹ́ pé àwọn ọkùnrin ni ó wà ní ìdí rẹ̀. Bóyá nítorí pé wọ́n tètè ń jáde ní ó fà èyí àtipé ó jẹ́ iṣẹ́ àánú.

Yàtọ̀ si ìwé ẹ̀rí onípò kìn-ín-ní tí ó jẹ́ òṣùwọ̀n tí ó kéré jù lọ fún olùkọ́ láti ṣe ìṣẹ́ olùkọ́, àǹfààní wà fún olùkọ́ yòówù láti fi kún ìmọ̀ rẹ̀, kí ó



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

gba oyè mọ́ oyè kí ó sì di òjọ̀gbọ́n ní ẹnu iṣẹ́ yìí. A fi ìdí èyí múlẹ̀ nínú ewì tí Ìṣọ̀lá kọ ní ìrántí Ọjọ̀gbọ́n Oláṣùpọ̀ Ọjẹ́dòkun nínú *Àfàìmọ̀ àti àwọn Àròfọ̀ mìíràn* (1978) níbi tí ó ti ṣe àpèjúwe rẹ̀ pé:

Òòyì ìwé dá lójú baba Káyọ̀dé
Ọmọ Àwẹ̀ró akọ́nìmákùsíbìkan (o.i. 11)

Ohun mìíràn tí a rí tọ́ka sí nípa iṣẹ́ olùkọ́ ní òde òní nì àṣà yíyan akẹ́kọ̀ọ́ bí ọrẹbìnrin èyí tì kò sí ní ayé àtijọ́. Bóyá nítorí pé ọ̀pọ̀ òbí kò fi ọwọ́ sí ẹ̀kọ́ àwọn obìnrin ni ayé àtijọ́ tàbí ìbẹ̀rù wà ní ọkàn àwọn olùkọ́ ní ìgbà náà ni kò jẹ́ kí èyí fi ìdí múlẹ̀ ṣùgbọ́n ní òde òní, kìí ṣe pé àwọn olùkọ́ ọkùnrin ń yan akẹ́kọ̀ọ́ obìnrin bí olólùfẹ́, wọ́n tún ń fẹ́ àwọn olùkọ́bìnrin ẹgbẹ́ wọn ní ìyàwó. Bákan náà, kìí ṣe pé ó jẹ́ ìwà tí ó burú kí olùkọ́kùnrin máa fẹ́ obìnrin ẹgbẹ́ rẹ̀ níwọ̀n ìgbà tí wọ́n bá ti pinnu láti gbé ara wọn sílẹ́ ṣùgbọ́n àbùkù rẹ̀ ni kí ojú ọkùnrin má gbé ibì kan, bí wọ́n tí ń fẹ́ dúdú ní Òkè-odò ni pupa tí ó wà ní Ìsàlẹ̀-odò ń dá wọn lórun tí wọn yóò sì máa dá wọn lọ́kàn le pé èkùrọ́ ni alábàákú ẹ̀wà gẹ́gẹ́ bí Ajàní ṣe ṣe fún Àṣàkẹ́ àti Ṣadé nínú *Ó le Kú.*

Àkíyèsí mìíràn tí a lè ṣe nípa iṣẹ́ olùkọ́ ní òde òní ni pé ìwé ẹ̀rí olùkọ́ni ń fún olùkọ́ ní àǹfààní láti ní ẹ̀bùn àti ọgbọ́n ìkọ́ni èyí tí wọ́n lè ṣe àmúlò rẹ̀ láti ṣe àṣeyege nínú ìgbékalẹ̀ wọn. Nítorí pé akẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfààní láti lọ fún kọ́mọ-n-wò-ọ́ fún àkókò kan nígbà tí ó wà ni ilé-ẹ̀kọ́, èyí ń fún un ní àǹfààní láti ṣe àtúnṣe níbikíbi tí ó bá ti ṣe àṣìṣe. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ fún àwọn oníwèé mẹ́fà tí ó gba iṣẹ́ olùkọ́ ní ayé àtijọ́ nítorí pé ìwé ẹ̀rí wọn kìí ṣe ti olùkọ́.

## Àfiwé Iṣẹ́ Olùkọ́ Láyé Àtijọ́ àti Lóde Òní

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìdàgbàsókè ń dé bá àwùjọ àti ẹ̀dá àwùjọ síbẹ̀ àwọn àbùdá kan wà tí ó jẹ́ ti ìpìlẹ̀ tí ó sì ń ran àwùjọ wa lọ́wọ́ títí di òní. Bí a ti rí àwọn ìhùwàsí tí ó ṣe é mú yangan lára àwọn olùkọ́ ayé àtijọ́ tí a kò sì fẹ́ kí wọ́n parun náà ni a rí àwọn tí ó nílò àtúnṣe kí ètò ẹ̀kọ́ lè peregedé. Bákan náà ni àwọn ìhùwàsí kan wà lóde òní láàrín àwọn olùkọ́ tí kò sí láàrin wọn ní ayé àtijọ́.

Ilé-ẹ̀kọ́ ti gbọ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ ní òde òní débi pé akẹ́kọ̀ọ́ kò nílò láti kúrò ní abúlé rẹ̀ títí ti yóò fi parí ilé-ẹ̀kọ́ girama. Kò sí àǹfààní kí akẹ́kọ̀ọ́ bẹ̀rẹ̀ ní ibi kan kì ó lọ sí àdúgbò tàbí ìlú mìíràn lọ parí ẹ̀kọ́ rẹ̀ mọ́ lóde òní nítorí pé ènìyàn ti pọ̀ sí i, ilé-ẹ̀kọ́ ti pọ̀ sí i bẹ́ẹ̀ ni ìjọba sì pèsè olùkọ́ sí àwọn ìgbèríko. Kódà ní agbègbè mìíràn, ilé-ẹ̀kọ́ girama ti wà tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò wọ̀

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

bí ó bá ti jáde. Abúlé tí kò bá ní ilé-ẹ̀kọ́ girama yóò ni ọkan ní abúlé tí kò jìnnà sí i gẹ́gẹ́ bí ètò tí ìjọba ṣe lóde òní.

Ohun mìíràn nípa iṣẹ́ olùkọ́ ní òde òní ni pé àǹfààní wa fún ènìyàn láti lọ ṣe iṣẹ́ ní ibi tí ó wù ú àti ìpele tí ó wù ú. Lónìí, bí a ti ri àwọn tí ó ní ìwé ẹ̀rí ilé-ẹ̀kọ́ gíga yunifásìtì ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ náà ni a ní wọn ní ilé ẹ̀kọ́ girama. Àjọ tí ó ń mójútó ètò ẹ̀kọ́ ní ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan yàtọ̀ nítorí náà, ènìyàn lè kúrò ní ìpínlẹ̀ kan lọ gba iṣẹ́ ní ìpínlẹ̀ mìíràn.

Ní òde òní, olùkọ́ ti ń múra bí ó tí tọ́ àti bí ó ti yẹ. Ìmúra olùkọ́ ní ayé àtijọ́ ní í ṣe pẹ̀lú wíwọ aṣọ òyìnbó pẹ̀lú tái nikan ṣùgbọ́n ní òde òní, kò pọn dandan kí olùkọ́ wọ aṣọ òyìnbó nìkan, ó lè wọ aṣọ ilẹ̀ wa ṣùgbọ́n èyí yòówù tí ó wọ̀ gbọ́dọ̀ wà ní ìwọ̀ntúwọ̀nsì. Bí ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ ṣe lè múra dáadáa náà ni àwọn olùkọ́ lè múra, kódà, wọ́n lè de tái nígbàkúgbà láìsí ẹni tí yóò mú wọn sí i.

Bí ojúṣe ṣe wà fún àwọn olùkọ́ láyé àtijọ́ náà ni ó wà ní òde òní. Ilé-ẹ̀kọ́ àti ọ̀gá tí ó dáńgájíá máa ń ní oríṣìíríṣìí ìgbìmọ̀ tí ó ń ṣe àmójútó ìlé-ẹ̀kọ́. Bí alága ṣe wà fún àwọn ìgbìmọ̀ yìí ni akọ̀wé àti àwọn ọmọ ìgbìmọ̀ wà bẹ́ẹ̀ ni wọ́n gbọ́dọ̀ jábọ̀ iṣẹ́ wọn fún gbogbo ilé ní òpin ọdún. Ọgbọ́n lílo ìgbìmọ̀ yìí ń mú kí àbójútó tí ó péye wà fún ilé-ẹ̀kọ́ ó sì ń mú iṣẹ́ àkóso rọrùn fún ọ̀gá ìlé-ẹ̀kọ́.

Ohun mìíràn nípa ìṣẹ́ olùkọ́ láyé àtijọ́ àti ní òde òní ni wí pé onírúuru nì wọ́n, bí a ti rí àwọn onínúure láàrin wọn náà ni àwọn ìkà àti ọ̀ṣónú wà. Èyí kò yẹ kí ó jẹ́ ìyàlẹ́nu nítorí pé onírúuru nì ẹ̀dá nílé ayé bẹ́ẹ̀ ni àbùdá kálukú yàtọ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé oríṣìíríṣìí ẹ̀kọ́ lórí bí a ṣe ń ṣe sí akẹ́kọ̀ọ́ nì olùkọ́ tí kọ́ nígbà tí ó wà ní ìlé-ẹ̀kọ́, kò lè ṣàìsí ọ̀kọ̀ọ̀kan tí kò ṣe àmúlò ẹ̀kọ́ yìí. Bí a ti rí àwọn olùkọ́ bí Pàdé Àdìó tí ó jẹ́ "olójú-bá-mi-dérù-bọmọ-mi", tí a rí Hábákúkù Òdúṣọ̀tẹ̀ bí "ọ̀ṣónu" ní ayé àtijọ́ náà ni wọ́n wà lóde òní. Bákan náà ni a ní àwọn bí Ṣẹ́gun Adéníyì tí ó fẹ́ràn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó sì kọ ìrẹ́jẹ ní ayé àtijọ́ àti ní òde òní. Òmìnira wà fún olúkọ́ láti na ẹgba ní ìlé-ẹ̀kọ́ ní òde òní ó kàn jẹ́ pé àwọn òbí ní àǹfààní láti fi ẹ̀hónú wọn hàn bí olùkọ́ bá ṣí àǹfaàní yìí lò.

**Ìmọ̀ràn**

Àgbékalẹ̀ Ìṣọ̀lá nípa olùkọ́ àti ìṣẹ́ olùkọ́ ṣí ojú wa sí àwọn kòṣeémánìí tí olùkọ́ tí ó peregedé gbọ́dọ̀ ní láti ṣe aṣeyege nínú ìṣẹ́ rẹ̀ lóde òní. Olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ ọlọ́yàyà àti ẹni tí ó kó akẹ́kọ̀ọ́ mọ́ra. Ó gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó fi ìfẹ́ hàn sí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ nítorí èyí nì yóò mú kí akẹ́kọ̀ọ́ fi ọkàn sí ẹ̀kọ́ kí ó sì ní ìfẹ́ láti dúró nínú ìyàrá ìkẹ́kọ̀ọ́.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ohun mìíràn bí ìmọ̀ràn fún iṣẹ́ olùkọ́ lóde òní ni pé àǹfààní gbọ́dọ̀ wà fún olùkọ́ láti lo ẹgba ṣùgbọ́n èyí gbọ́dọ̀ jẹ́ ní ọ̀nà tí ó yẹ. Olùkọ́ kò gbọ́dọ̀ máà rìn káàkiri pẹ̀lú ẹgba lọ́wọ́ nítorí èyí yóò mú ìpayà bá akẹ́kọ̀ọ́. Nígbà tí akẹ́kọ̀ọ́ bá ṣe ohun tí kò dára, olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ kí ó tó nà án nìtorí èyí nì yóò jẹ́ kí ó lè yàgò fún irú àṣìṣe bẹ́ẹ̀ ní ọjọ́ iwájú. Ìdánìlẹ́kọ̀ọ́ tí ó péye gbọ́dọ̀ wà fún olùkọ́ lórí ìbániwí bẹ́ẹ̀ ni ìtanijí gbọ́dọ̀ wà fún òbí lórí ìhùwàsí wọn nígbà tí olùkọ́ bá bá àwọn ọmọ wọn wí.

Ìmọ̀ràn mìíràn lórí iṣẹ́ yìí ni pé àǹfààní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ òòrèkóòrè gbọ́dọ̀ wà fún olùkọ́ láti bá ẹgbẹ́ pé. Ìrírí ṣe àgbà ọgbọ́n bẹ́ẹ̀ ni onírúurú ẹ̀kọ́ àti ohun èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni ni ó ti wà lónìí. Olùkọ́ tí ó bá fẹ́ bá ẹgbẹ́ pé gbọ́dọ̀ máa lọ sí àpérò àti ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ àwọn onímọ kí ìmọ̀ rẹ̀ lórí iṣẹ́ tí ó ń kọ́ má ba à jóbà, Ìjọba pàápàá gbọ́dọ̀ ṣe àtìlẹ́yìn fún olùkọ́ tí ó ń kọ́ àwọn iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan. Ìjọba tún lè fún wọn ní àǹfààní ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ tàbí sísan lára owó ìforúkọsílẹ̀ fún irú àpérò bẹ́ẹ̀.

Ohun tí a tún lè mú wá gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ràn fún iṣẹ́ olùkọ́ lóde òní ni pé kí ìwúrí wà fún olùkọ́ nípa fífún wọn ní owó àjẹmọ́nú tí ó ṣe é mú yangàn pàápàá jù lọ, àwọn tí ó wà ní ìgbèríko. Ìjọba lè fi owó díẹ̀ lé sí ti àwọn tí ó wà ní ìgbèríko kí ó lè jẹ́ kóríyá fún wọn nítorí ọ̀pọ̀ ni kò fẹ́ ṣiṣẹ́ ní ìgbèríko mọ́. Bákan náà, owó ọ̀yà olùkọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ sísan déédé láti jẹ́ kóríyá fún wọn.

**Àgbàlọgbábọ̀**

Mánigbàgbé ni iṣẹ́ Ìṣọ̀lá lórí iṣẹ́ olùkọ́ nínú àwọn ìwé tí a yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ yìí nítorí ó ṣí ojú wa sí àwọn ohun tí ó jẹ́ àṣà Yorùbá nípa ṣíṣe àlejò àti fífi ọ̀wọ̀ fún àwọn tí ó jẹ́ olóore ẹni. Iṣẹ́ yìí tún jẹ́ kí á mọ ipò tí iṣẹ́ olùkọ́ àti olùkọ́ wà ní ilẹ̀ Yorùbá ní ayé àtijọ́ àti bí ó ti wà lóde òní, ó sì jẹ́ kí á wo àwọn ọ̀nà tí a lè gbà ṣe àtúnṣe ní ibi tí ó kù díẹ̀ káàtó sí.

A lérò pé àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ olùkọ́ ní ayé àtijọ́ àti lóde òní yóò tún tẹ̀ síwájú jù báyìí lọ nítorí pé oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀tun ni ó ti ṣẹlẹ̀ sí iṣẹ́ yìí lẹ́yìn tí Ìṣọ̀lá gbé àwọn ìwé yìí jáde nítorí ìlò àwọn ohun èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni bí ẹ̀rọ ayárabíàṣá, ẹ̀rọ ayélujára, fíìmù, pùròjẹ́kítọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ pẹ̀lú ìrìnàjò afẹ́ ti mú kí ìkọ́ni àti iṣẹ́ olùkọ́ rọrùn báyìí lóde òní ju ayé àtijọ́ lọ.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**Àkójọ Orúkọ Ìwé**

Afọláyan, M.O (2008) "The Thinker Pedagogy and the Enduring Legacy of Relevancy and Humanity: The case of Akínwumí Ìṣọ̀lá, The Master Teacher" nínú Akíntúndé Akínyẹmi àti Tóyìn Fálọlá (olótùú) *Emerging Perspectives on Akínwumí Ìṣọ̀lá,* Trenton: Africa World Press Inc. o.i. 917-927.

Akínyẹmí A. àti Fálọlá, T. (olótùú) (2008) "Akínwumí Ìṣọ̀lá: Biographical Outline" *Emerging Perspectives on Akínwumí Ìṣọ̀lá,* Trenton: Africa World Press Inc. o.i. 469-477.

Federal Republic of Nigeria (2004) *National Policy on Education.* Lagos: Government Press.

Ìṣọ̀lá, Akínwumí (1974) *Ó Le Kú,* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Ìṣọ̀lá, Akínwumí (1978) *Àfàìmọ̀ àti àwọn Àròfọ̀ Mìíràn,* Ìbàdàn: University Press Limited.

Ìṣọ̀lá, Akínwumí (1990) *Ogún Ọmọdé.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Jedo, S.O. (1981) *A Text Book on Principles and Practice of Education.* Àkúrẹ́: Ola-Awe printing Works.

Ọpádọ̀tun Olátúnjí (2003) *Òǹkọ̀wé àti Ìwé-kíkọ Alátinúdá* (Àtúnṣe Kìn-ín-ní). Ọyọ́: Odumatt Press and Publishers.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY